O WE YORUBA

Ojo o w u r ẹ lo mbi olowo alon, olowo gẹlẹ tẹ, iwọfa gẹlẹtẹ. Ojo ko ba ẹni kan ṣ'ọrẹ, eni ẹji ri ni ẹji ap. Ojo pata, pata, pata balẹ, ọmọ adiẹ sare bẹe ọl.

# ELETI OFE

A-NJU-WỌN KO ṢE WI LEJO

ASOJE OFO

Wompari kan ko si, eni nm kukute ara re lo oni. Eru ko b'elo, eni to t'ejo mọlẹ, oluwarẹ ni ebọ m o. Aṣa mbeyele s e r e, ẹlyẹlẹl oyo, ẹlyẹle ... ṣete

VOL. XII No. 664. LAGOS, SATURDAY, FEBRUARY 27 — MARCH 4, 1960. KỌBỌ MEJI (2·


# Ibosi Ole, Oyinbo Kan Nsise Gbomogbomo

Irohin tẹ wa lọw, nipa ọkunrin Alalijọnu kan ti o lọ gba aṣoju lọdọ awọn ọlọpa wipe, ẹnikẹni ti o ba ṣa ti sọnu larin ilu, ki nwọn wa sọ fun on, awọn alijẹnnu on yio si ba wọn wa ẹniti o sọnu.

Lakoko na ni ironin nkan kakiri pe awọn enia nsọnu Bi ọmọde ti nsonu latin ilu bẹni agba nsọnu. Nigbati ọkuurin na lọ fi ara rẹ han awọn ọlọpa inu wipe on yio jẹ oluranlowo fun won, awon olopa si gba bẹ ṣugbon nwon bere lowo rẹ pe, kini iwo yio fi wa awon enia na ti o sonu tabi ọna wo ni iwo yio ma fi wa won? o dahun wipe, on ni awọn Alijannu mẹwa ti nba on ṣiṣẹ, awọn alijannu nwọnyi lo mba on wa ibiti awọn enia na ba si. Nitotọ ọkunrin na si nṣe gẹgẹbi ileri rẹ, gbogbo ẹniti o ba ti sọnu, lo nri he ninu igbo, ninu ọdan ati ni arin meji afonifoji ... oke. Bi awọn ọlọpa ba si bere lọwọ ẹniti nwọn ri he na wipe kilo gbe lọ de ibẹ, tabi kini ohun ti o nṣe nibiti nwọn ti gbe ri he na, ko si eyiti o le sọ gẹgẹbi o ti ṣe rin ki o to de ibẹ. Ọgọrun pọnun ni o ngba fun ọmọ ti o ba sọnu.

Awọn ọtẹlẹmuyẹ ofoju si nwọn si ufi ọkan baria. Nwọn wa ridi aṣiri alijọnu iaọ ti ọkunrin na nlo.

Ibẹ ni awọn ọlọpa ti ragabu rẹ, nwon gbe ju si itimọle, awọn otẹlẹmuyẹ reti ki awọn alijonu wa gba okunrin na kuro ni itimole, ṣugbon nwon ko wa rara. Agbare gbbo nwon ju Alalijannu na sẹwọn odun gboro.


THE NATIONAL BANK
Of Nigeria Limited

Incorporated in Nigeria in 1938
Paid up Capital £1,130,000
Bankers to the Western Region Government of Nigeria
HEAD OFFICE
37, MARINA, LAGOS NIGERIA
22 Branche Throughout Nigeria including
IBADAN, ABEOKUTA, IJEBU-ODE,
OSHOGB O, OWO, ONDO, ILESH
ILARO, BENIN-CITY, WARRI
SAPELE ABA, KANO, ZARIA, JOS

LONDON OFFICE
1 THROGMORTON AVENUE. E.C. 2.
Manager: F. O. Tyrrell.

Telephone: London Wall 4303
Cables & Telegrams Natbanger London.
Head Office Representatives in London
E. Akinwumi Doherty.
CORRESPONDENTS
NEW YORK, PARIS HAMBURG.


# Ibukun Ni Iranti Oninu're



Ijọba gbogbo-gbo ti ile Nigeria tun ti gbe oko oju omi nla kan si ori omi. A so oko titun na ni oruko ologbe Bode Thomas.

Ologbe yi je Ojoto Ijoba gbogbo-gbo fun igboke gbodo awon oko ofurufu, ti oju irin ati ori omi nigba aiye re

Eyi fi han pe Ijoba Nigeria ko gbagbe rẹ ati wipe dajudaju irepo yio wa larin awon oselu wa

A dupe pupo fun Ijoba gbogbo-gbo ti Nigeria

Bode Thomas Orun re o!


POLOWO
OJA RE SI IWE ELETI-OFE

# Nigerian Ports Authority

## INVITATION TO TENDER

The Nigerian Ports Authority invite tenders from catering contractors, who must be resident in Port Harcourt, for the supply of the following foodstuffs at the Authority's Canteen Port Harcourt, for a period of one year :-

| | |
|---|---|
| FOOD | ;Garri with ariboro; okoro; egusi; ologbu or water-leaf soup; boiled rice or rice with palm oil or ground-nut stew; boiled beans; fried yam; boiled yam; pounded yam; ekuru; akamu; mai-mai; agidi; tapioca with coconut, fried plantain; boiled stock-fish; roasted and boiled corn. |
| FRUIT | Oranges; bananas; pine-apple; paw-paw apples kolanut; bitter kola; alligator pepper. |
| CONFECTIONERY | Cake; biscuits; buns; eggs and others |
| BEVERAGES | Tea; Coffee; Ovaltine. |
| TOBACCO | Cigarettes (all brands), and snuff. |

2. A copy of the Tender Form and Agreement may be obtained from the Port Manager, Nigerian Ports Authority Rivers Ports, Port Harcourt, on a deposit of £5 and the completed form should be returned to him in sealed envelope marked " CONFIDENTIAL - CATERING TENDER" so as to reach him not later than Thursday, 10th March, 1960.

3. The deposit of £5 will be refunded on submission of a bona fide tender.

4. The Nigerian Ports Authority do not bind themselfs to accept the lowest or any tender.

A.R. Cordon
Secretary to the Authority.

18th Feb, 1960. N.P.A. Notice No. 405.

# E Wa Haya Ile

Oporan ida kokan ati ida meji-meji awon ile ti o dara wa ni Araromi, Apapa nibiti o ni anegun fun bihaya nisosi odo ona, ko si jinna jo ibeje mowa lo fun Moto lati kotu o'opa, Apapa nitosi ona Eko titun si Kirikiri.

Enikeni ti o ba fe haya, ki o kowe si Asolu ebi Oloye Oluwa ni 1, Akibo Street, Araromi Apapa tabi si Loya won ni 20, Reclamation Road, o kojusi ile ise I. E. D. B. L'Eko.

I. ISHOLA OLUWA.
Agbejoro

KIN KIN L'O KU



Irohin t si wa leti fe̩re̩ wipe Gomina agba ti fi oye Olotu abo ilu ati t'awon olopa (Minister of Defence and Police) le Olotu Ijoba Apapose owo.

Ey' ẹ̀ẹ̀n mo wa ninu gidigidi Ominira ti o mbo na yio soju emi gbogbo wa.

## EGBE N.C.N.C NTUKA NI ILORIN

ILORIN. Agbo irohin wipe awon omo egbe N.C.N.C. ati omo egbe N.P.C. ti bere si tuka ni enitere, ejitere l o f i o r i pamo s i abe egbe Action Group. Ninu ipade egbe Afenifere (A.G.) ti nwon se koja lo laipe yi nigboro ilu Ilorin, a gbo pe Alhaji Sanusi a t i Mallam Kusimo ti ya kuro ninu egbe N.C.NC. ati N.P.C.

Mallam Kusimo so wipe idi re ti on fi ya kuro ninu egbe na ni wipe, on mo idi na tabi wipe ki on ni mimo ohun ti olori egbe na nse nipa gbo gbo ohun ti o nkoja lo ni akoko yi.

(Wo yoko loju ewe kejo)


## Ogun Aran ej Inu

Aradan Worm Expeller ogun aran patki fun omode ati agba okunrin ati obirin. Ra igo kan loni ya gbogbo awon aran buruku ti o nba e ja ninu danu. Bio ti npa aran bewa o npa eyin wọn. Wa ra tire ki o to tan. Igo kan je 2/6 Owo eko ti e 1/.

THE EGRA TRADING
ARADAN STORES
18, Denton Bridge Street
P. O. Box 2 Ebute-Metta





# E Ma Ka Iwe Irohin

ELETI-OFE LOOSE







adlẹ.

Aṣa meji kan ni awọn arufin tun ṣẹṣẹ gbe de Awon ti o nṣe owo aiyederu ati awọn to nji ọmọ gbe. Iru awọn ti a wi wonyi, ogba ẹwọn ko jọ won loju mọ, ko sile mu won yi iwa wọn pada, a yafi ki nwon lo igbesi aiye won ninu ogba ẹwọn awon agbe re yoku ti o ba se akiyesi pe lagbaja lọ ko pada bọ mọ ko ni fẹ dan iru iwa bẹ wo mọ.

Nitoripe awon arufin nwonyi ofin ijoba ko jọ won loju mọ beni bi a ko ba pe Ijihanji ẹru ko ni ba iji o daju pe awon ko le dan iru re ni asa wo nile Parsase.

Emi ni,
Alfa Kẹrẹkẹdu

---

**AIYE LA BA IFA AIYE LA BA IMALE, OSAN GA NCAN NIGBAGBỌ DE**

(Lati ẹnu Ẹṣọ)

Nigbati awọn Igbagbọ bẹrẹ ẹsin ti nwọn, ọmọbinrin kan dahun wiṣe nkan ti nwọn ri mọlẹ ninu afin ọba yi, jẹ ẹda ti o lẹsẹ mẹrin o si jẹ alawo meji.

Ọba Oluwo sọ fun won pe on gbadun nyin, sugbọn o ku diẹ, ki nwọn si lo foko na.

Awọn babalawo lo kan nisisiyi, nwọn da ara won si meji, nwọn bẹrẹ si jan ọpẹle wọn mọlẹ, orikin nda Ikin alagbigba ndagbigba, oniporun njan tire mọlẹ. nigbati Olukuluku wọn ti dibo tirẹ tan nwọn wa pe Ajowo, ohun ti a ba jẹ wo lo ngun regerege.

Gbogbo wọn bẹrẹ si ja ibo, ọkan dahun pe, ẹranko ni ohun na, ekeji ni ẹlẹsẹ mẹrin ni nkan na, ẹkẹta ni ẹranko na ni iwo gagara, ẹkẹrin ni alawo meji ni ẹranko na. Nigbati o se ọkan wipe malu ni nkan na.

Ọba ati Ijoye fi ori kori Ọba dahun pe, o dara mo gbo ohun ti ẹ wi o ku awọn onimale.

Awọn Imale fi ori kori, nwọn yan tira fun ara won lati ke.

Anfyan ti nwọn da ki nwọn to ke tira na ni wipe, ohun kohun to wu ki nwọn ri mọlẹ ninu afin ọba yi, ki Ọlọrun sọ nkan na di oku olobinrin enia.

Ni nwọn ba bẹrẹ si i kewu nigbati nwọn kewu tan nwọn so fun ọba wipe, Kabiyesi, ki ọba kio pe, oku obinrin kan ni eri mọle ninu afin.

Ọba ja wọn niro wipe, o ri malu ni on ri mole, awọn Imale dahun pe, Ọlọrun ti awon ko npuro, ki nwọn hu. oku oku na jade ki a wo.

Nigbati nwọn hu jade o di oku enia.

Lati ọjọ na wa ni Oluwo ti gba esin Imale, o si gba awon Alawo ati Igbagbo laye lati ma ba esin ti won niso.

---

**ỌGBA ẸWỌN KO JỌ AWỌN ARUFIN LOJU MỌ**

Olotu,

Nitotọ awa gba wipe Ijọba Gẹsi lo rọrun ju gbogbo ijọba awọn orilẹ ede lọ boya ẹwẹ nitoripe awọn Gẹsi lo ti ngbe wa jo lati kekere lo jẹki ofin wọn rọ wa lọrun bẹ.

Ṣugbọn aṣa buruku ti awọn janduku enia ba gbe wọ ilu ti o le ba ilu jẹ, o yẹ ki ijọba ṣe ofin ti o lagbara lori wọn ki iru iwa bẹ le dawọ duro.

Ni apẹrẹ ẹniti o ba pa ẹnikeji o yẹ ki a pa on na pẹlu ko si apania ti o jẹ gba wipe ki a mu ida koja lori on. Bi ko ba si iru ofin bayi nwon ko ba ma pa enia kakiri bi ẹni pa

---

# Itan Anobi Liasu

(Apa 8)

Lati owo L mọmn Ajakuta

Anọbi Liasu gbera kuro ni ori oke, nibiti o ma nlọ gbadura, o ni kori si igboro ilu Jerusalem. Irohin ti lọ ba Jasibali wipe Anọbi Liasu mbọ ni igboro, ati pe ni ojude re ni yio gba koja lọ.

Nigbati Jasibali gbo ọrọ yi, o tagiri dide, o mu ọpa rẹ dani, o si duro ni tente ori ile ọba o nso Anobi Liasu ki o yọ ni okere, ki o ba le ta ase fun.

Ṣugbọn awọn enia ti o po lehin Liasu ko jeki o le da Liasu mọ.

(Wo yoku lojo ewa keria)

---

**HINDU SANKARA'S**
**Religious Art Jewelleries**



Perfumes, Charms, Mohammedan charms, Amulets, Vedic Prayers, Kawaches. Faithful Reproductions of Hindu Gods in the Jewelleries.

*Postal order by Air Mail for Catalogues and Literature.*

HINDU SANKARA, 421 Archway Road, London, N.6, England

# ELETI - OFE

A-NJU-WỌN KO SE WI L'EJỌ

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRAM

28, Kosoko Street, Lagos. "ELETI - OFE LAGOS"

P. O. Box 467 Phone 23370

VOL. XII. NO. 664 SATURDAY FEB 27- MAR. 4, 1960


## Ko Omo Re L'ona Ti Yio Rin ...

Nigbati o wa ni ewe, nitoripe bi o ba dagba tan, ki o ma ba ya kuro nina rẹ". Awọn Yoruba ma npowe bayi wipe, "lati kekere ni Imale ti nkọ ọmọ rẹ l'aṣọ" tabi lọna keji ẹwẹ, "lati kekere ni a ti npekan iroko, nitoripe bi o ba dagba tan, apa ko ni ka mọ".

Nigba aiye Ologbe Dr Henry Carr l'akoko ti o nṣe Alabojuto awọn ile ẹkọ nigbero ilu Eko, on l'o paṣẹ wipe ki awọn bẹrẹ si lo iwe kekere kan ti awọn npe ni "Iwe ti o nkọni gẹgẹbi a ti nhuwa" (Moral Instruction) o si fi aṣẹ si pe ki awọn Olukọ ma ṣe itumọ inu iwe na si eti awọn ọmọ akẹkọ.

Nipa gbigbọ ọrọ inu iwe na, olukuluku awọn ọmọ akẹkọ nkọ lati ma huwa rere, awọn ọmode nb'ọwọ fun agba, awọn korira ole jija, ko si afojudi, awọn si etiraka pa ofin Ọlọrun mọ, awọn ofin na niwọnyi:-

1. Iwọ ko gbọdọ ni Ọlọrun miran pẹlu mi.
2. Iwọ ko gbọdọ fi ori bale fun ohun kan.
3. Iwọ ko gbọdọ fi oruko Ọlọrun seri irọ.
4. Ranti ọjọ isinmi lati lo ni mimọ.
5. Bọwọ fun baba ati iya rẹ.
6. Iwọ ko gbọdọ paniа.
7. Iwọ ko gbọdọ se agbere tabi panṣaga
8. Iwọ ko gbọdọ jale
9. Iwọ ko gbọdọ jẹri eke
10. Iwọ ko gbọdọ se ojukokoro

Ṣugbọn ni ode ti oni, ko si iruфẹ ẹko bawonyi mọ kakiri awọn ile ẹkọ wa eyi ni idi re ti ọpọlọpọ iwa buruku fi wọpọ larin awọn majesin wa ode oni yi.

Imoran awa Ọmọ iroyin Eleti-Ofe fun ẹnyin Okawe wa ni wipe, ki olukuluku wa fi awọn ọmọ re ni eti, ki awọn si gbiyanju lati ma ko won ni awon ofin wọnyi lati kere ewe wọn.

Ki a ... ko won ni eko iwe lasan, nitori ki nwọn le ... ere lẹhin-wa ọla.


MORTGAGES ON ALL CLASSES OF PROPERTIES
Write For Particulars ...
SPENCER ...
BRIDGE ...
N.W. ...



LIVE WELL
EAT WELL
eat
"De FACTO"


## Iya Tunfulu



Eniti a nwo nina aworan yi ni ọba Obinrin Elisabeth Keji, ọba Gesi, on ni agbọ wipe nigbati o loyun, kosi bi ọmọ na ti gbogbo aiye ti bẹrẹ si pukiki rẹ pe yio bimọ loni, lọla, lotunla ki o to wa bi ọmọ na lọjọ Friday 12th Feb, 1960.

A gbọ pe o di ọdun ọgọta-lọgọrun ti a ba iru ọmọ bayi sori oye ọba nigba aiye Ọba Obinrin Victoria.

## Itan Anobi Liasu

(Apa ...)

**Lati owo Lee ... Ajakuta**

Nibiti o ... nga oja lati ri Anobi Liasu, ibe ni eyi ti gbe, o si yi loju lati ibi giga rẹ, ... ode gbangba, agbara rẹ si fọ, gbogbo awọn ti o ri ..., lo sa sẹhin nigbati awọn ri pe ori gba ọna ... apa gbọtọ, ẹsẹ gbọtọ, ibẹ ni awọn aja jadẹ wa, awọn si jẹ oku Jasibali.

Ọba ti o jẹ ọkọ Jasi-bali ẹniti o ti mọ iru agbara nlanla ti iyawo rẹ ni, ti o si mọ pe on ko ni idamẹwa iru agbara ti iyawo on ni, ti o si ti gbọ iru ara ti Anobi Liasu ti fi da, nitori na, ọba gba Liasu ni alejo o si teriba fun Ọlọrun Liasu. Lẹhin eyi o mbo, ẹ o gbọ bi Anobi Liasu ti se goke lọ si ọrun.

(Kuru Pari)

## QLORUN MAJE KI ẸLẸRU SURO NIDI ẸRU RẸ

Iyale buruku na ronu ba wo ni on yio gbe gba ti ọmọ rẹ yio fi di iyawo ọmọ ọba dipo ọmọ Orogun rẹ.

L'igbẹhin o mu omo rẹ lowo ni oganjo oru nwon doriko ile omo oba o wo inu iyara omo orukan ti nse omo orogun rẹ ti o si ti fa fun Ọmo ọba ni aya. O mu omo orogun rẹ jade o si fa omo re sinu iyara.

Gẹgẹbi owe ti o so wipe "Agbigbo l'oru ori osi wa aiye osi ti o bu gbe ni ko ni deru pani. Boyi ni apere ohun ti o sẹle larin awon ọmọ mejeji yi.

Nigbati won de idaji ọna Iyale bere lowo omo orukan pe "Bawo ni ile omo oba ti dun to ? Omo na da lohun pe "Ile omo oba tabi wahala.

O ni ti awon Iyale ba wa kio ni owuro oẹ ni a fi odakun bi awon erubinrin ba kio kelebẹ ati ikun ni a nfan jo nwon bi awon Iyawo ile ba bere onje, epo epo ni a fi ma nwon irẹsi fun won. O ni bi oko ba wo iyara ni ale, ni lati kegbe ki gbogbo ugbo mọ.

(Wo yoku loju ewe kele)

## AWỌN MUSULUMI OGBOMỌSỌ GBADURA FUN AKINTỌLA



Oloye S.L. Akintola, ti ise-Premier ilu Ino-Orun awon ijo Musulumi ti ilu Ogbomoso se akanse adura funu ati iyawo re loni ipo ti Olorun gbe de yi. Oniwasi ojo na so wipe, bi o tile je pe Akintola ki nse Imale, sibe, o gba Olorun gbọ, o si bewo fun esin Imale.

# Awon Egbon Tunfulu



Awọn neti ti e nwo ninu aworan yi ni awọn egbọn Tunfulu na. Eyi ti o wa lori igi ni Prince Charles, eni ni H.R.H. Prince of Wale, ọba iẹla, en ni akọbi ọba ilu Oyinbo.

Eyi ti o joko sile je obinrin, on ni omo keji ti nwọn bi ki nwọn to wa bi Tunfulu si iẹta, Tunfulu na yio bere si gba edegbejo poun lọdọdun titi yio fi di omo odun mọkanlelogun.




## Jamba Ile, Jamba Ode, Oluwa Mafi Jamba Se wa

Itan yi ki nse atoso rara bi ko se ohun ti o sele ni ilu Baghdad ni igba aiye atijo ni. Itan yi yio fun wa ni opolopo eko, ogbon ati oye.

Okunrin onisowo kan wa ni ilu Baghdad ni igba Laiye-Laiye, okunrin yi ama se owo re lati ilu kan si ekeji.

A ma ra oniruru awon ohun alumoni, ati ma ma ra awon erukunrin ati erubinrin pelu.

Bi a ko tile ri, nigbon opolopo wa ti ri ka nipa ise, tabi ki a si ti ri gbo lati odo awon agbalagba pe, ni igba ijoun, nwon a ma so awon eru mole ni inu oja fun tita.

Ni ojo kan okunrin onisowo yi lo si ilu kan lati ta ati lati ra awon oja fun ise.

Nigbati o de ibi eru, nwon ti ta gbogbo awon eru ti o wa tan, ayafi eru kan pere l'osoku sile.

Eru na si je odomkunrin arewa.

Okunrin onisowo na bere lowo olowo re pe ki o ta fun on, olowo re si da owo po ku le e.

Eyi je iya lara papo fun la ti ri pe owo poku ni a ba la ori oni darodiła yi.

O bere lowo olowo re pe 'Erue ti o fi ta eru re yi si ita' o dahun po ...

A la a ba ... dara ni iwa re si ni ofofo ati eke.

(Wo yoku loju ewe kele)

## OLORI ALATAKO IJỌBA APAPỌṢE

Ọgbẹni Dr. Chike Obi, ojogbon nnaw ino 'ne lo so wipe' ninu igbimo ile (House of Representatives)' enikan soso o...



Ilo'gba ... ra Oloye Do... Oro si a ba gbo ... Foto. [illegible]

# Baba Tunfulu



Baiti a'ewo yi ni Prince Phillip ti ise oko oba obinrin, Elizabeth Keji ti'ilu Gesi. On ni a ba yo ayo omokunrin jojolo ti Olorun fi tu a lore ni ose to koja. ku ewu o! Baba Tunfulu.

# Itan Bi Ile Se Ko Lati Teriba Fun Orun

Lati owo Eso

Aajo lo nse awo ile aiye,
Abemo lo nse awo ile orun,
Awon mejeji lo nse omo awo Edumare. Awon ni a difa fun Lojo ti ogun mbe laiye, ti ogun mbe lorun, ti ile ko lati fori bale fun orun.

Ejiogbe.

Lasenkose Olorun wa, akun ti Olorun si koko da ni ile ki oto wa se ada ohun gbogbo sori ile na.

Ni ojo kan Orun ati Ile se ode lo sinu igbo, sugbon awon ko ri ohun kan pa, ayafi oku emo kan soso. Nigbati awon de enu ala arin aiye ati ara orun, awon pin oku Emo na. Ariyanjiyan wa bere larin awon ode mejeji awonyi. Orun so wipe, se emi ni egbon emi lo ye ki ngbe ori, nitoripe oke ni ori ngbe oke ni emi na si wa. Ile taku wipe ko ni lati gbe ori lo nitori ti on ni oku Emo na, lori mi lo si ngbe.

Orun ko wipe afi bi on ba gbe ori Emo na lo, Ile papa taku pe bi o ba tigba ni so fi fun ko ni mu ori re lo. E ma ka iwe Irohin Eleti-Ofe, iyoku di ose ti o mbe.


## Kere o!

A ti ni orisirisi egbogi fun arun Inarun ati arun Jedi-jedi, (Bitter Tonic Liquid of Life) Tete wa ra tire, l'okunrin ati l'obinrin. ki o to tan.

J.A. AJAO BROTHERS
MEDICINE STORES
7, Egerton Road, Lagos





AVAILABLE AT:-
AKOSHILE BROTHERS
5, BALOGUN STREET WEST.
P.O. BOX 599. LAGOS.



## The Nigerian Medicine Stores

"GBOMORO"

EGBOGI ATATA FUN IGBONA OMODE, IBA ORERE, INU-IWO ATI AIPERI



IGBONA ATI ORISIRISI ARUN MIRAN TI O MA NYO OMODE LENU NIGBA EHIN HIHU.

"GBOMORO"

Dara pupo fun omo ikoko tabi Tunfulu. Kosemani ni egbogi yi fun omo abiyamo. Ajebidan ni i oruko re nje. Ko ni fa Jedijedi tabi igbe-orin fun omode, tete wa ra tire ni sobu wa.

THE NIGERIAN MEDICINE STORES
4, TINUBU SQUARE, LAGOS

Tabi ni awon Eka wa ni :-

Port Harcourt, Jos, ati Ibadan.

## Jagunjagun Oju Omi Ile Nigeria



Awọn ọmọ ogun oju omi ti a nwo ninu aworan yi, ni awọn omo ogun ile Nigeria ti nwọn nṣiṣẹ ninu oko ogun H. M. N. S. Nigeria. Gbogbo awon jagunjagun inu oko na fere je enia dudu ara ile Nigeria ayafi awon die ninu won ti o je oga lo Oyinbo.

Wo gbogbo won bi nwon ti duro sansan ti ọgako (Commandant) si nye imura won wo.

# Atilogu, Ijo awon Ara Ila-orun



Ọkunrin ti a nwo ti o dabi egungun ninu aworan yi, je ara agbegbe Ila-Orun ti o njo iru ijo kan ti nwon npe ni ijo Atilogu.

Ijo na fere ... ijo ti Yorba kan ti nwon npe ni ijo Bata ijokijo ni ijo bata, sugbon nigbati awon opo enia ba njo ijo Atilogu, nwon o ma fi inu ka isise won, nitoripe ki nwon ie mo akoko ti nwon ma gbera so ati ki nwon le jo ijo na daradara.

## Jamba Ile, Jamba Ode Oluwa Mafi Jamba Se wa

(O bere lojo ewe karun

La'si ani ani, oniso wo yi ra erukunrin na nitori ewa re, o ni on yio fi se omo odo, on yio si sora nipa iwa re.

Ni ... yi de ile ... fi iwa re pamo o si n se dara dara de'po ti olowo re fere gbogbo iwa ti a fi t... mi owo poku

Daju-daju, odidi ni owe ti awon Yoruba npa wipe 'Ko si bi a ti le se Ifa ti ko ni hu iwa ekuro.'

Erukunrin yi nowo iwa re buburu yi si iyawo olowo re.

(Koi ti pari)

## ỌLỌRUN MAJẸ KI ẸLẸRU KURO NIDI ẸRU RẸ

Iyale mu omo orakan lo si ile, osi pada lo se gbogbo awon nkan won y fun omo re lati mu lo n ile oko.

Nigbati ile mo, a w o n iyale re wa ki, o si fi ese da awon Fulani, awon erubinrin wa o fun kun imu ati kelebe fo won Para

Awon iyawo ile bere epje o fi epo ep won iresi fun won.

Nigbati ile su ti omo oba wa lati wo iyara re o kan ilekun o si wo inu iyara, beni omo yi fa igbe ta bayi pe.

'Oko wo ile! 'Oko wo ile! gbogbo awon ara ile ati ara adagbo si tu jade.

Pelu afoni folu ni omo oba san iyara pelu iyawo aiyederu yi, bi ile ti nmo, o bere lowo awon iyale ba yi pe, 'Ba wo ni eti ri iwa iyawo si'?

(Iyoku di ose t'o nbo

Bhojsons

Annual

# SALE

FANTASTIC REDUCTION

THE BIGGEST BARGAINS

NOW IN TOWN ... GREAT OPPORTUNITY!

COME ARE OUR SALE PRICES

MANS SHOP

SINGLETS & BRIEFS 3s

T SHIRTS (white only) 6s | NYLON SHIRTS 15s

TIES 2s 6d

STARTEX DUTCH DRESSING SHIRTS (full sleeves ... slightly shop soiled) originally 32/6d ... now 20s

SOCKS 4s

KHAKI SHORTS 6s

CHILDREN SEC

CORDUROY JEANS 7s

BUSTER SUITS (cow boy type) 6s

CHILDREN PYJAMAS 9s

All cotton white SOCKS 1s 6d | CHILDREN SHOES 9s 6d

Toys 33⅓ % off

LADIES SEC

All Cotton Printed DRESS MATERIAL 36" wide (Continental Prints) 3s and up a yd

A lot of BLOUSES 2s & 4s each

SWIMWEAR 10s (at throw away prices) and up

BEAUTIFUL DRESSES £1

HORIZONTAL STRIPE BLOUSES 9s 6d

FURNISHINGS

CURTAIN MATERIAL (Printed) 48" wide 5s yd.

TOWELS (Jaquard designs (.... colours) 3s 6d

PILLOW CASES 2s 3d (2 colours only) | BED SHEETS 11s 6d 54x90 white)

HOUSEHOLD

STAINLESS STEEL DESSERT SPOONS & FORKS 1s 3d each

GLASS TUMBLERS 6d ea | coloured TUMBLERS 1s 6d each

RECORDS 5s, 10s 15s & 20s

... and 1,001 MORE BARGAINS! FOR BIGGER AND BETTER BERGAINS ...

Bhojsons

N.B. REMEMBER ... TODAY & MONDAY WE ARE OPEN (all departments) till 7.00 p.m.

BHOJSONS STORE, OYINGBO P.O. BOX 63, EBUTE METTA


# Oloye Fadairo Dupe Fun Igbegasoke Si Ipo Minister

ILARO. Lojo isinmi ose ti o koja lo yi ni Oloye E.A.-A. Fadayiro se isin idupe fun si igbegasoke re si ipo Oloru nl na ijoba Iwo-orun ile Nigeria.

Gbogbo enenoba ati awon Ijoye ti o mbe ni Iwo-orun lo peju-pese si ibi isin idupe na. Oloye Obafemi Awolowo ati awon egbe re pesepe wa sibi isin idupe na, awon ebi, ati ore Oloye yi wa nibe.



Alufa agba, Enlowo, A.W. Howells lo se iwasu ojo na. Awon orin isale owonyi ni awon egbe Oloye ko fun olon ileisin Christ Church Ilaro ni agbegbe Egbado.

AKANSE ORUN FUN IGBEGA SOKE OLOYE FADAYIRO

1 Ipo re o dara o, Olola Fadayiro
Ipo re wu mi lopolopo, m o si ma de temi
Nko ni ko ko na mi lowo, nko ni ko ko na mi lara
Ipo re o dara o, Olola Fadayiro
Ipo re wu mi lopolopo, mo si ma de be o
Bori ba ojoba lola o, mo si de be o
2. Ile re a dara o, a toro minimini
Ile re a sanni lopolopo lagba ara Edumare
Ipo re a tun gasi o, olola Padayiro
Ipo re a gasi lopolopo lagbara Edumare
B'ori ba ngbara lola o, mo si ma ni temi
Nko ni ko ko na mi lowo' nko ni ko ko na ni lara.
3. Ipo ola dara o, ipo elege.
Ipo yen wu mi lopolopo mo si ma de temi
Nko ni ko ko na mi lowo' nko ni ko ko na mi lara
Ipo ola dara o, ipo elege,
4. Aiye re a loyin o nse mirin mirin
Aiye re wu mi lopolopo mo si ma ri temi
Nko ni ko ko na mi lowo, nko ni ko ko na ni lara.

Aiye re o loyin o, o nse mirin mirin
Aiye re loyin lopolopo o se mirin mirin,
B'ori ba ngbare lola o mo si ma ri temi.

# EGBE N.C.N.C NTUKA NI ILORIN

Fun Azikiwe lati lo joye Baba egbe igbimo Senate, loju ti o ri o dabi eni po o si fi gbogbo ise re jona.

Iyanu lo si je fun on lati ri N.C.N.C. nkawo sokun fun o N.P.C.

Alhaji Sanusi ti a wiyi je ti nse alaga fun egbe N.C.N.C. ni arinmeji Igboro Ilorin (Ilorin Central) nigba ti nwon ndibo nilu Ilorin laipe yi.

# ELETI-OFE DARABA

Published by The Union Printing and Publishing Company 28, Kosoko Street, P. O. Box 467 Lagos Phone 23337